# IWAASU LORI OKE, APA KIN-IN-NI

## Matteu 5:1-48

## ẸKỌ 19 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: “Nitorina ki ẹnyin ki o pé, bi Baba nyin ti mbẹ li ọrun ti pé” (Matteu 5:48).**

Jesu wá si ayé pẹlu Ihinrere ifẹ Rẹ̀, ṣugbọn diẹ ni aye mọ̀ ninu iwa Onigbagbọ́ tabi awọn oore-ọfẹ irẹlẹ ti o n mu ki igbesi aye layọ̀. Awọn ara Romu ni o n ṣe akoso ayé nigba naa, ijọba irin ni a si n pe ijọba wọn, nitori agbara wọn ati iwa ipá ati ìkà ti wọn fi n ṣe ijọba. Awọn ara Romu ni ogunlọgọ awọn ọmọ-ogun ti o lagbara; awọn jagunjagun n bá ẹranko jà laaarin pápá iṣere lati fi agbara wọn hàn; awọn eniyan si n lakaka kikankikan lati tayọ ara wọn ninu eré sisá, ni fifo soke, ni jiju nnkan si okere ati ninu awọn ere miiran. Igbesi aye awọn talaka ko si layọ rara nitori awọn ọlọrọ ati awọn alagbara lo n fi wọn ṣe ijẹ. Nigba ti ọba nla ba n gun kẹkẹ rẹ̀ lọ, awọn ẹrú yoo maa sare niwaju, wọn yoo si maa kigbe fun gbogbo awọn ti wọn duro pe, “Ẹ tẹ eekun yin ba.” Awọn ọmọde ni lati ṣiṣẹ karakara to bẹẹ gẹẹ ti ninu wọn kò fi le dagba soke; itọju diẹ ni a si n fun awọn obinrin. A maa n kẹgan ẹnikẹni ti kò ba lagbara tabi ti o n ṣe jẹ́jẹ́.

### Ifẹ Ọlọrun

Nigba naa ni Jesu de pẹlu ẹkọ Rẹ̀ ti ifẹ, iwa pẹlẹ, inu tutu ati inu rere. O sọ fun awọn eniyan pe, “Alabukún-fun li awọn òtoṣi li ẹmí: nitori tiwọn ni ijọba ọrun … Alabukún-fun li awọn ọlọkàn-tutù: nitori wọn o jogún aiye. Alabukún-fun li awọn alãnu: nitori nwọn ó ri ãnu gbà.

Nigba ti Jesu ri ọpọ eniyan ti wọn ti jade wá lati ri iṣẹ Rẹ̀, O gun ori oke lọ, nibi ti aaye pupọ wà, ki awọn eniyan ba le fi eti silẹ si I nigba ti O ba n sọrọ. Jesu kò fi ọrọ Rẹ̀ ṣura fun awọn aṣayan diẹ, ṣugbọn O waasu rẹ ki olukuluku ba le gbọ́ ki o si ri igbala.

### Otoṣi ni Ẹmi

O bẹrẹ iwaasu Rẹ̀ nipa sisọ fun awọn eniyan ohun ti yoo mu inu wọn dùn. “Alabukún-fun (tabi ẹni ti o ni ayọ̀) li awọn òtoṣi li ẹmí.” Itumọ rẹ̀ ni pe wọn gbọdọ jẹ́ onirẹlẹ; O si sọ pe, ti wọn ni ijọba Ọrun. Awọn eniyan n wo ọna fun Kristi lati gbé ijọba kan kalẹ ninu ayé, ki O si bi ijọba Romu wó pẹlu agbara, ki O ba le tu awọn Ju silẹ kuro ni oko ẹrú. Ṣugbọn Jesu sọ fun wọn lati ibẹrẹ wá pe Oun ni ọna ti o yatọ si eyi, lati gbà fi jere ọkàn eniyan: awọn ọlọkàn tutù ni yoo jogún ayé. Kò ye awọn eniyan bi awọn nnkan wọnyii ti ṣe le ri bẹẹ, ṣugbọn a le fi oju igbagbọ́ ri i pe, awọn ọmọ Ọlọrun ti wọn n la igba irẹnisilẹ wọn kọja nisisiyii yoo ṣe akoso ayé ni igba Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun lẹyin ti Jesu ba tun pada wa.

### Awọn Onilaja

“Alabukún-fun li awọn onilaja: nitori ọmọ Ọlọrun ni a ó ma pè wọn.” Eniyan kò le jẹ Onigbagbọ́ ki o si maa sọ̀ tabi ki o maa jà. Nigba ti Jesu ba fi alaafia Rẹ̀ sinu ọkàn wa, a oo mu ẹmi ijọngbọn kuro. Ọdọmọkunrin kekere kan ti o jẹ Onigbagbọ wá si ile lati ile-iwe, o si sọ fun iya rẹ pe: “Iya, njẹ o mọ ọna ti o dara lati dá eniyan lẹkun ni ṣiṣe ohun ti o kò fẹ ki wọn ṣe? Iwọ saa jẹ ki wọn maa ṣe e lọ, wọn yoo si dẹkun. Ọdọmọkunrin kan bẹ̀rẹ si i ti mi, o si n fi ẹsẹ rẹ̀ ta mi nipa nigba ti o dabi ẹni pe o fẹ́ bẹ̀rẹ wahala. Ṣugbọn mo fi ọkàn mi gbadura ninu mi, mo si ṣe bi ẹni ti ko ri i, o si duro.” Jesu n fun olukuluku ọmọ Rẹ̀ ni agbára lati ṣẹgun nigba ti a ba yiiri wọn wò.

### Ijọba Awọn Ọmọde

Jesu fẹran awọn ọmọde O si wi pe, “Ẹ jẹ ki awọn ọmọ kekere ki o wá sọdọ mi, ẹ má si ṣe da wọn lẹkun: nitoriti irú wọn ni ijọba Ọlọrun” (Marku 10:14). Ni igba kan nigba ti Jesu wà ninu Tẹmpili, awọn ọmọde kọrin pe, “Hosanna fun Ọmọ Dafidi,” eyi kò si dùn mọ́ awọn alufaa ninu; ṣugbọn Jesu wi pe, “Ẹnyin kò ti kà a, Lati ẹnu awọn ọmọ-ọwọ ati awọn ọmọ-ọmú ni iwọ ti mú iyin pé?” Jesu n fẹ ki awọn ọmọde maa kọrin iyin si Oun. Nigbakuugba ni O maa n pe awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, ani awọn ti o dagba pẹlu, ni “ọmọde” nitori O wi pe ayafi bi eniyan bá rẹ ara rẹ̀ silẹ, ki o si gbọran gẹgẹ bi ọmọ kekere, wọn ki yoo le wọ Ọrun (Matteu 18:3).

### Imọlẹ Rẹ̀ N Tàn

Lẹyin igba diẹ, Jesu sọ ninu iwaasu Rẹ̀ pe, “Ẹnyin ni imọlẹ aiye. Ilu ti a tẹ̀do lori òke kò le farasin.” Ni igba miiran, Jesu wi pe, “Emi ni imọlẹ aiye,” nitori idi eyi a ri i pe Jesu n fẹ ki awọn ọmọ-ẹyin Oun dabi Oun.

Bawo ni a ṣe le jẹ imọlẹ? Nipa gbigba wa là, ki a si ni Jesu ni igbesi-ayé wa. Bi Imọlẹ ba wa ninu wa, Oun yoo tàn jade. A tun pa a laṣẹ fun wa pe: "Ẹ jẹ ki imọlẹ nyin ki o mọlẹ tobẽ niwaju enia, ki wọn ki o le mã ri iṣẹ rere nyin, ki nwọn ki o le ma yin Baba nyin ti mbẹ li ọrun logo." Awọn eniyan ki i saba fi eti silẹ si ẹni ti o wi pe Onigbagbọ́ ni oun, ṣugbọn wọn a maa ṣọ́ igbesi-ayé rẹ̀ lati ri pe o dabi Kristi.

Ko ṣẹṣẹ di igba ti imọlẹ wa ba di nla ki awọn eniyan to le ri wa. A sọ fun wa pe, a le ri imọlẹ iṣana lati mile kan ninu okunkun biribiri. Ẹni kọọkan ninu awọn ọmọ Ọlọrun ni o ni imọlẹ, o si gbọdọ jẹ ki o tàn ni ibi ti Ọlọrun ba fi i si.

**"Jesu fẹ ki a tan bi imọlẹ**
**Bi imọlẹ fitila ninu oòkùn;**
**Laye okunkun yii a ni lati tàn;**
**Iwọ at'emi nibi ta ba wà."**

Ẹni kan tun ti wi pe, imọlẹ igbesi aye eniyan ti o n tan imọlẹ si gbogbo aye jẹ́ akojọpọ itanṣan oorun kékèké, ti o n mọlẹ daradara **ni gbogbo igbà. Eyi ni ohun ti o ṣe pataki: jẹ ki imọlẹ rẹ tàn – ni gbogbo igbà**. Awọn eniyan kò ni igbẹkẹle ninu awọn wọnni ti wọn ri igbala ni ọsẹ kan, ti wọn si jẹ ki imọlẹ wọn tàn; ni ọsẹ keji, ki wọn faseyin, ti imọlẹ wọn si kú. Ohun iyanu ni lati wà ninu igbala, ki o ba le ni ohun ti yoo ran ọ lọwọ, ti yoo si maa yin Ọlọrun logo, ni ile-iwe tabi ni ibikibi. Agbara wà ninu Ẹjẹ Jesu lati pa wa mọ́ ninu igbala ni gbogbo igbà.

### Ọlọrun N Rí Ọkàn

Jesu n sọrọ lọ nipa Ofin, ati pe awọn eniyan n kùna aṣẹ rẹ. Awọn akọwe ati awọn Farisi, ti wọn jẹ́ ẹlẹsin wi pe awọn n gbọran si awọn Ofin Mẹwaa, wọn si n ṣọra pupọ ki ẹnikẹni ma ṣe ri i pe wọn rú ọ̀kan ninu wọn. Ṣugbọn wọn ko ni ifẹ rárá ninu ọkàn wọn fun Ọlọrun tabi fun awọn ẹlẹgbẹ wọn, Wọn a duro, wọn a si gbadura gigùn ki wọn ba le fi ara hàn bi eniyan mimọ́, lẹyin naa wọn a si "jẹ ile awọn opó run" (Matteu 23:14). Boya wọn n beere, fun itọju ile isin, owo ti o pọ ju eyi ti awọn obinrin alaini wọnyii le san lọ, bayii ni wọn si n gba ohun gbogbo ti wọn ni lọ. Jesu sọ fun wọn pe wọn ti fi "ọ̀ran ti o tobiju ninu ofin silẹ laiṣe, idajọ, ãnu, ati igbagbọ́" (Matteu 23:23).

Ofin wi pe, "Iwọ kò gbọdọ pania"; ṣugbọn Jesu wi pe, Onigbagbọ́ kò tilẹ gbọdọ ni ohun kan ninu rẹ̀ ti yoo jẹ ki o fẹ́ pa eniyan. Ẹni kan le ṣe alai pa eniyan; ṣugbọn bi o ba korira, o ti di apaniyan. Jesu wi pe, "Ẹ fẹran ara nyin" – ati awọn ọ̀ta yin pẹlu. O wi pe bi ẹyin ba fẹran kiki awọn ti o fẹran yin, bawo ni ẹyin ti ṣe sàn ju awọn ẹlẹṣẹ lọ? Jesu fẹran wa nigba ti a jẹ́ ọ̀ta Rẹ̀, Oun si n fẹ ki a fẹran awọn ẹlẹgbẹ wa to bẹẹ gẹẹ ti a le fi ṣe oore fun wọn, ki a si gbadura fun won, ki awọn naa ba le ri igbala. Ọlọrun n ran oorun sori awọn ẹlẹṣẹ gẹgẹ bi O ti n ran an sori awọn Onigbagbọ́, ọ̀jọ̀ si n rọ̀ si ori gbogbo eniyan bakan naa.

Nigba ti Jesu fi aṣẹ yii lelẹ pe, "Nitorina ki ẹnyin ki o pé, bi Baba nyin ti mbẹ li ọrun ti pé," ki i ṣe pe O n fun wọn ni ofin titun. Ọlọrun ti sọ ohun kan naa fun Abrahamu pe, "Ma rìn niwaju mi, ki iwọ ki o si pé" (Gẹnẹsisi 17:1). Nigba ti Jesu wi pe, "Alabukún-fun li awọn oninu-funfun: nitori nwọn ó ri Ọlọrun," O fun wa ni aṣiiri jijẹ pipé. Ọkàn funfun ni isọdi mimọ́, iwa mimọ́, nipa eyi ti a fi n ri pipé Onigbagbọ́ gbà. "Ẹ mã lepa alafia pẹlu enia gbogbo ati ìwa mimọ́, li aisi eyini kò si ẹniti yio ri Oluwa" (Heberu 12:14).

### AWỌN IBEERE

1. Ki ni gbọdọ jẹ́ iṣesi wa bi a ba ṣe inunibini si wa nitori Jesu?
2. Bawo ni a ṣe le jẹ ki imọlẹ wa tàn?
3. Bi arakunrin wa ba ni ohun kan ninu si wa, ki ni a gbọdọ ṣe nipa rẹ̀?
4. Ki ni Jesu kọ́ ni nipa yiyá ni ni nnkan ati fifi fun awọn ẹlomiran?
5. Bawo ni Jesu ṣe fi aṣẹ fun wa lati bá awọn ọta wa lò?
6. Njẹ Jesu n fẹ ki a jẹ́ pipé?
7. Kọ́ awọn ẹsẹ ọrọ Ọlọrun ti o bẹrẹ pẹlu "Alabukún-fun" sori.